61

# PETERU KEJI

**(A.D. 66)**

ORI 1.

**Ìkíni.**

SIMONI Peteru, iranṣẹ ati Aposteli Jesu Kristi, si awọn ti o ti gba iru iyebiye igbagbọ kan naa pẹlu wa, ninu ododo Ọlọrun wa ati ti Jesu Kristi Olugbala: (Rom 1:1; 1 Pet 1:1; Rom 1:12; 3:21–26.)

2. Ki oore-ọfẹ ati alaafia maa bi sii fun yin ninu imọ Ọlọrun ati ti Jesu Oluwa wa, (1 Pet 1:2; ẹsẹ 3,8.)

**Idagba ninu ìmọ̀ otítọ́.**

3. Bi agbara rẹ̀ bi Ọlọrun ti fun wa ni ohun gbogbo ti i ṣe ti iyè ati ti iwa-bi-Ọlọrun, nipa ìmọ̀ ẹni ti o pè wa nipa ogo ati ọlanla rẹ̀: (1 Pet 1:5; 1 Tess 2:12.)

4. Nipa eyi ti o fi awọn ileri rẹ̀ ti o tobi pupọ ti o si ṣe iyebiye fun wa: pé nipa iwọnyìí ni ki ẹyin lè di alabapin ninu iwa Ọlọrun, nigba ti ẹyin bá ti yọ kuro ninu ibajẹ ti nbẹ ninu ayé nipa ifẹkufẹ. (2 Kor 7:1; Ef 4:24; 1 Jhn 3:2; 2 Pet 2:18–20.)

5. Ati nitori eyi naa paapaa, ẹ maa ṣe aisinmi gbogbo, ẹ fi ìwàrere kún igbagbọ, ati ìmọ̀ kún ìwàrere; (2 Pet 3:18; Kol 2:3.)

6. Ati airekọja kun ìmọ̀; ati suuru kún airekọja; ati iwa-bi-Ọlọrun kún suuru; (A.A. 24:26.)

7. Ati ifẹ ọmọnikeji kun iwa-bi-Ọlọrun; ati ifẹni kun ifẹ ọmọnikeji. (1 Tess 3:12.)

8. Nitori bi ẹyin ba ni nkan wọnyìí ti wọn bá sì pọ̀, wọn ki yoo jẹ ki ẹ ṣe ọ̀lẹ tabi aláìléso ninu ìmọ̀ Oluwa wa Jesu Kristi. (Jhn 15:2; Tit 3:14.)

9. Nitori ẹni ti o ba ṣe alaini nkan wọnyìí, o fọju, kò lè riran ni okeere, o si ti gbagbe pe a ti wẹ oun nù kuro ninu ẹṣẹ rẹ̀ atijọ. (1 Jhn 2:11; Ef 5:26; 1 Jhn 1:7.)

10. Nitori naa, ará, ẹ tubọ maa ṣe aisinmi lati sọ ipe ati yíyàn yin di dajudaju: nitori bi ẹyin ba nṣe nkan wọnyìí, ẹyin kì yoo kọsẹ̀ lae.

11. Nitori bayìí ni a o pèsè fun yin lọpọlọpọ lati wọ ijọba ainipẹkun ti Oluwa ati Olugbala wa Jesu Kristi.

**Orisun imọ otitọ.**

12. Nitori naa emi o maa mura lati maa mu nkan wọnyìí wá si iranti yin nigba gbogbo bi ẹyin tilẹ̀ ti mọ̀ wọ́n, ti ẹsẹ̀ yin si mulẹ̀ ninu otitọ tí ẹyin ní. (1 Jhn 2:21.)

13. Emi si rò pe o yẹ, niwọn igba ti emi ba nbẹ ninu àgọ́ yìí, lati maa fi iranti ru yin sókè; (2 Tim 4:6; Jhn 21:18,19.)

14. Bi emi ti mọ̀ pe, bíbọ́ àgọ́ mi yìí silẹ kù si dẹdẹ, ani bi Oluwa wa Jesu Kristi ti fi hàn mi.

15. Emi o sì maa ṣaapọn pẹlu, ki ẹyin lè maa ranti nkan wọnyìí nigbagbo lẹhin iku mi.

16. Nitori ki i ṣe bi ẹni ti ntọ ìtàn asán lẹhin ti a fi ọgbọ́nkọ́gbọ́n là silẹ̀, ni awa fi agbara ati wiwa Jesu Kristi Oluwa hàn yin, ṣugbọn ẹlẹri Ọla-nla rẹ̀ ni awa jẹ́. (1 Tim 1:4; Matt 17:1; Mk 9:2.)

17. Nitori ti o gba ọla ati ogo lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun baba, nigba ti iru ohùn yìí fọ̀ si i lati inu ogo nla naa wa pe, "Eyi ni ayanfẹ Ọmọ mi, ẹni ti inu mi dùn si gidigidi." (Matt 3:17; Luk 9:35.)

18. Ohùn yii ti o ti ọrun wá ni awa si gbọ, nigba ti awa nbẹ pẹlu rẹ̀ lori oke mímọ́ naa. (Matt 17:6.)

19. Awa si ni ọ̀rọ̀ asọtẹlẹ ti o fẹsẹmulẹ jù bẹẹ lọ; eyi ti o yẹ ki ẹ kiyesi bi fitila ti ntàn ni ibi òkùnkùn, titi ilẹ yoo fi mọ́, ti irawọ owurọ yoo si yọ lọ́kàn yin. (1 Pet 1:10,11; Psm 119:105; Ifh 22:16.)

20. Ki ẹ kọ́ mọ eyi, pe kò si ọkan

ninu asọtẹlẹ̀ inu iwe-mímọ́ ti o ni itumọ ìkọ̀kọ̀. (Rom 12:6.)

21. Nitori asọtẹlẹ kan kò ti ipa ifẹ eniyan wá rí; ṣugbọn awọn eniyan nsọrọ lati ọdọ Ọlọrun bi a ti ndari wọn lati ọwọ Ẹmí Mimọ wá. (2 Tim 3:16; 1 Pet 1:11; A.A. 1:16.)

ORI 2.

**Awọn olukọni èké ti yoo mu ẹkọ òdì wọnu Ijọ.**

SUGBỌN awọn wòlí èké wà laarin awọn eniyan naa pẹlu, gẹgẹ bi awọn olukọni èké yoo ti wa laarin yin, awọn ẹni ti yoo mu àdámọ̀ ègbé wọ inu yin wa, ani ti yoo sẹ́ Oluwa ti o rà wọ́n, wọn o si mu iparun ti o yara kánkán wá sori ara wọn. (1 Tim 4:1; Jud 18; 1 Kor 6:20.)

2. Ọpọlọpọ ni yoo si maa tẹ̀lé iwa wọbia wọn; nipa awọn ẹni ti a o fi maa sọ ọ̀rọ̀-òdì si ọ̀nà otitọ.

3. Ati ninu ojukokoro ni wọn o maa fi yin ṣe èrè jẹ nipa ọ̀rọ̀ ẹ̀tàn; idajọ ẹni ti kò falẹ̀ lati igba atijọ wá, iparun wọn kò sì tòògbé. (1 Tim 6:5; 2 Kor 2:17; Deut 32:35.)

**Ìjìyà fun awọn alaiwa-bi-Ọlọrun.**

4. Nitori pe bi Ọlọrun kò bá dá awọn angẹli sí tí wọn ṣẹ̀, ṣugbọn ti o so wọn si isalẹ̀ *ọ̀gbun, ti o si fi wọn sinu ọ̀gbun okùnkùn biribiri ninu ìfipamọ́ titi de idajọ; (Jud 6; Jhn 8:31; Ifh 20:1,2; Rom 10:7; 1 Pet 3:19; Job 33:22.)

5. Ti kò si da ayé igbaani si, ṣugbọn o pa Noa pẹlu awọn meje miran mọ́, oniwaasu ododo, nigba ti o mu ìkún-omi wá sori ayé awọn alaiwa-bi-Ọlọrun; (Gen 7:1; Heb 11:7; 1 Pet 3:20.)

(4) *Ọgbun ni 'Tartarus' ni ede Griki, tabi 'Abyss' ni ede oyinbo. Ọgbun okùnkùn yìí ni a nfi awọn ẹ̀mí ti o ṣe aigbọran si de ọjọ idajọ. Ohun naa si ni a tun npe ni isà-òkú (Hades/Sheol) nibi ti a nfi ọkan awọn òkú alaigbagbọ si de ọjọ́ ìdájọ́ bakannaa. Jesu papaa lọ sibẹ lati waasu fun wọn. (1 Pet 3:19,20.) Nikẹhin, iku, isa-oku, ati ọ̀gbun yìí ni yoo lọ si ina ọrun-apadi (Gehenna) pẹlu gbogbo awọn alaigbagbọ, ati ẹmi-èṣù ati Eṣu. (Ifh 20:10,14; 21:8.)
Eyi si ni iku keji, ibi idanilóró laelae.

6. Ti o sọ awọn ilu Sodomu ati Gomora di eérú, nigba ti o fi ìparun pátá-pátá dá wọn lẹbi, ti o fi wọn ṣe apẹẹrẹ fun awọn ti yoo jẹ́ alaiwa-bi-Ọlọrun; (Gen 19:24; Jud 7; Num 26:10.)

7. Ti o si yọ Lọti olootọ, ẹni ti iwa wọ̀bìà awọn eniyan buburu bà ninu jẹ́: (Gen 19:16; 2 Pet 3:17.)

8. (Nitori ọkunrin olootọ naa bi o ti ngbe aarin wọn, ti o nri ti o si ngbọ́, lojoojumọ ni ìwà buburu wọn nba ọkàn otitọ rẹ̀ jẹ́;)

9. Bi o ba ri bẹẹ, Oluwa mọ bi a ti nyọ awọn ẹni iwa-bi-Ọlọrun kuro ninu ìdánwò ati bi a ti npa awọn aláìṣootọ́ ti a njẹ níyà mọ́ de ọjọ ìdájọ́: (1 Kor 10:12; Jud 6; Luk 16:22,23.)

10. Ṣugbọn paapaa awọn ti ntọ ara lẹhin ninu ifẹkufẹ eerí, ti wọn si ngan awọn ijoye, awọn ọ̀dágbá, aṣe-tinuẹni, wọn kò bẹ̀rù lati sọrọ ẹ̀gàn si awọn ẹni-ògo. (2 Pet 3:3; Jud 8; Tit 1:7.)

**Iwa ati iṣe awọn ẹlẹtan.**

11. Bẹẹ ni awọn angẹli bi wọn ti pọ̀ ni agbara ati ipá tó, wọn kò dá wọn lẹjọ ẹ̀gàn niwaju Oluwa. (Jud 9.)

12. Ṣugbọn awọn wọnyìí, bi ẹranko ìgbẹ́ ti kò ni èrò, ẹranko ṣá ti a dá lati maa mú pa, wọn nsọ̀rọ̀ ẹ̀gàn ninu ọ̀ràn ti kò yé wọn, a o pa wọn run patapata ninu ibajẹ ara wọn; (Jud 10.)

13. Wọn o si jẹ èrè aiṣododo, awọn ti wọn ka a si ayé jijẹ lati maa jẹ adùn ayé ni ọ̀sán. Wọn jẹ́ àbàwọ́n ati àbùkù, wọn njayé ninu àsè-ìfẹ́ wọn nigba ti wọn ba njẹ àsè pẹlu yin; (Rom 13:13; Jud 12; 1 Kor 11:20,21.)

14. Awọn oloju ti ó kún fún panṣaga, ti kò sì lè dẹ́kun ẹ̀ṣẹ̀ dídá; ti ntan awọn ọkàn ti kò fi ẹsẹ̀ mulẹ̀ jẹ; awọn ti wọn ni ọkàn ti o ti fi ojukokoro kọ́ra; awọn ọmọ ègún: (ẹsẹ 18; Jud 11; ẹsẹ 3; Ef 2:3.)

15. Wọ́n kọ ọnà ti o tọ́ silẹ̀, wọn si ṣáko lọ, wọn tẹ̀le ọna Balaamu ọmọ Beori, ẹni ti o fẹran èrè aiṣododo; (Num 22:5,7; Jud 11.)

16. Ṣugbọn a ba a wi nitori irekọja

rẹ̀: odi kẹtẹkẹtẹ fi ohùn eniyan sọ̀rọ̀, o si fi opin sí wèrè woli naa. (Num 22:23; 23:28,30,31.)

**Èrè buburu wà fun awọn ẹlẹ́tàn.**

17. Awọn wọnyìí ni kanga ti kò ni omi, ikuukuu ti ẹ̀fúùfù ngbá kiri; awọn ẹni ti a pa òkùnkùn biribiri mọ́ dè titi lae. (Jud 13.)

18. Nitori igba ti wọn ba nsọ̀rọ̀ ihalẹ̀ asán, ninu ifẹkufẹ ara, nipa wọ̀bìà, wọn a maa tan awọn ti wọn fẹrẹ má ti i bọ́ tán kuro lọwọ awọn ti wọn wa ninu ìṣìnà. (Jud 16.)

19. Wọn a maa ṣe ileri ominira fun wọn, nigba ti awọn paapaa jẹ ẹru ìdíbàjẹ́; nitori ẹni ti o ba ṣẹgun ẹni, oun naa ni i si sọ ni di ẹrú. (Jhn 8:34; Rom 6:16.)

20. Nitori lẹhin ti wọn ba ti yọ tán kuro ninu eeri ayé, nipa mimọ Oluwa ati Olugbala wa Jesu Kristi, bi wọn bá sì tún fi ara ko o, ti a si ṣẹgun wọn, igbẹhin wọn a buru ju ti iṣaaju lọ. (Matt 12:45; Lk 11:26; 2 Pet 1:2.)

21. Nitori iba sàn fun wọn, ki wọn má mọ ọ̀nà ododo, ju lẹhin ti wọn mọ̀ ọ́n tán, ki wọn yipada kuro ninu ofin mímọ́ ti a fifun wọn. (Heb 6:4. 2 Pet 3:2; Jud 3.)

22.Owe otitọ naa ṣẹ si wọn lara, Ajá tun pada si èébì ara rẹ̀; ati ẹlẹ́dẹ̀ ti a ti wẹ̀ mọ́ tun pada nyíràá ninu ẹrẹ̀. (Owe 26:11.)

## ORI 3.

**Ileri ìpadàbọ̀ Jesu Kristi.**

OLUFẸ, eyi-ni iwe keji ti mo nkọ si yin; ninu mejeeji naa ni emi nru inu funfun yin soke nipa rírán yin létí;

2. Ki ẹyin lè maa rántí ọ̀rọ̀ ti a ti ẹnu awọn woli mímọ́ sọ ṣaaju, ati ofin Oluwa ati Olugbala wa lati ọdọ awọn aposteli yin:

3. Ki ẹ kọ mọ eyi pe, nigba ọjọ ikẹhin, awọn ẹlẹ́gàn yoo de pẹlu ẹ̀gàn wọn, wọn o maa rìn nipa ifẹ ara wọn (1 Tim 4:1; Jud 18; 2 Pet 2:10.)

4. Wọn o si maa wi pe, "Nibo ni ileri wiwa rẹ̀ gbé wà? lati igba ti awọn baba ti sun, ohun gbogbo nlọ bi wọn ti wà rí lati igba ọjọ yii wá." (Isa 5:9; Jer 17:15; Esk 12:22; Matt 24:48; A.A. 7:60; Matt 10:6.)

5. Nitori eyi ni wọn mọ̀ọ́mọ̀ ṣe àìfẹ́mọ̀, pe nipa ọ̀rọ̀ Ọlọrun ni awọn ọ̀run ti wà lati ìgbà atijọ, ati tí ilẹ̀ yọri jade ninu omi, ti o si duro ninu omi: (Gen 1:6,9; Heb 11:3; Kol 1:17.)

6. Nipa eyi ti omi bo ayé ti o wà nigba naa ti ọ si ṣègbé: (Gen 7:21,22.)

7. Ṣugbọn awọn ọ̀run ati ayé, ti nbẹ nisinsinyìí, nipa ọ̀rọ̀ kan naa ni a ti tòjọ bi iṣura fun iná, a pa wọ́n mọ́ de ọjọ idajọ ati iparun awọn alaiwa-bi-Ọlọrun. (ẹsẹ 10; 2 Tess 1:7; 1 Kor 3:13.)

**Akoko ati iṣẹ̀lẹ̀ fun ipadabọ Kristi.**

8. Ṣugbọn, olufẹ, ẹ máṣe gbàgbé ohun kan yii, pe ọjọ kan lọdọ Oluwa bi ẹgbẹrun ọdun ni o ri, ati ẹgbẹrun ọdun bi ọjọ kan. (Psm 90:4.)

9. Oluwa kò fi ileri rẹ̀ jáfara, bi awọn ẹlomiran ti ka ijafara sí; ṣugbọn o nmu sùúrù fun yin nitori kò fẹ́ ki ẹnikẹni ṣègbé, bikoṣe ki gbogbo eniyan wá sí ironupiwada. (Heb 10:37; Isa 30:18; 1 Pet 3:20; Rom 2:4.)

10. Ṣugbọn ọjọ Oluwa nbọwa bi olè ni òru; ninu eyi ti awọn ọ̀run yoo kọja lọ pẹlu ariwo nlá, ati awọn imọlẹ oju ọ̀run yoo si ti inu ooru gbígbóná gidigidi di yíyọ́, ayé ati awọn iṣẹ ti o wà ninu rẹ̀ yoo si jona luuluu. (Matt 24:43; 1 Tess 5:2; Matt 24:35; Ifh 21:1.)

11. Njẹ bi gbogbo nkan wọnyìí yoo ti yọ́ bẹẹ, iru eniyan wo ni ẹyin ìbá jẹ́ ninu ìwà-mímọ́ gbogbo ati iwa-bi-Ọlọrun.

12. Ki ẹ maa reti, ki ẹ si maa mura gírí de dide ọjọ Ọlọrun, nitori eyi ti awọn ọ̀run yoo gbiná, ti wọn yoo di yíyọ́, ti awọn imọlẹ rẹ̀ yoo si ti inu ooru gbigbona gidigidi di yíyọ́? (1 Kor 1:7; Tit 2:13; Psm 50:3; Isa 34:4; ẹsẹ 10.)

13. Ṣugbọn gẹgẹ bi ileri rẹ̀, awa nreti awọn ọrun titun ati ayé titun ninu

eyi ti ododo ngbé. (Isa 65:17; 66:22; Ifh 21:1.)

**Ọrọ ipari ati igbani-niyanju.**

14. Nitori naa, olufẹ, bi ẹyin ti nreti iru nkan wọnyìí, ẹ mura gírí, ki a lè ba yin ni alaafia ni àìlábàwọ́n, ati ni àìlábùkù loju rẹ̀. (2 Pet 1:10; 1 Kor 15: 58; Filp 2:15.)

15. Ki ẹ si maa kà á si pe, sùúrù Oluwa wa igbala ni; bi Paulu pẹlu, arakunrin wa olufẹ, ti kọwe si yín, gẹgẹ bi ọgbọn ti a fifun un; (ẹsẹ 6; 1 Kor 3:10; Ef 3:3.)

16. Bi o ti nsọ̀rọ̀ nkan wọnyìí pẹlu ninu ìwé rẹ̀ gbogbo ninu eyi ti ohun miran ti o ṣoro lati yé ni gbé wà, eyi ti awọn òpè ati awọn alaiduro nibikan nló, bi wọn ti nló iwe- mímọ́ iyoku, si iparun ara wọn (ẹsẹ 14; Heb 5:11; 2 Pet 2:14; ẹsẹ 2.)

17. Nitori naa ẹyin olufẹ, bi ẹyin ti mọ̀ nkan wọnyìí tẹlẹ̀, ẹ maa kiyesara, ki a má baa fi ìṣìnà awọn eniyan buburu fà yín lọ, ki ẹ si ṣubú kuro ni iduro-ṣinṣin yin. (1 Kor 10:12; 2 Pet 2: 18; Ifh 2:5.)

18. Ṣugbọn ẹ maa dàgbà ninu oore-ọfẹ ati ninu ìmọ̀ Oluwa ati Olugbala wa Jesu Kristi; ẹni ti ogo wà fún nisinsinyìí ati títí lae. Amin.

62

# JOHANU KINNI

**(A.D. 90)**

ORI 1.

**Ọ̀rọ̀ Ìṣáájú.**

EYÍ ti o ti wà ni àtètèkọ́ṣe, ti awa ti gbọ́, ti awa ti fi ojú wa rí, ti awa sì ti tẹjúmọ́, ti ọwọ́ wa sì ti dìmú, niti Ọ̀rọ̀ ìyè; (Jhn 1:1,14; 2 Pet 1:16; Jhn 20:27.)

2. Ìyè naa si ti farahàn, awa sì ti ri i, awa sì njẹ́rìí, awa sì nsọ niti ìyè ainipẹkun naa fun yin, ti o ti nbẹ lọdọ baba, ti o si farahàn fun wa; (Jhn 1:1–4; Rom 16:20; Jhn 21:24.)

3. Eyi ti awa ti rí, ti awa sì ti gbọ́ ni awa nsọ fun yin, ki ẹ̀yin pẹlu lè ni ìdàpọ̀ pẹlu wa: nitootọ́ idapọ wa si nbẹ pẹ̀lú Baba, ati pẹlu Ọmọ rẹ̀ Jesu Kristi. (A.A. 4:20; 1 Kor 1:9.)

4. Awa sì kọwe nkan wọnyìí si yin, ki ayọ̀ yin lè di kíkún. (1 Jhn 2:1; Jhn 3:29.)

**Títọ ipa ọ̀nà ododo.**

5. Eyi si ni iṣẹ́ ti awa ti gbọ́ lẹnu rẹ̀ ti awa si njẹ́ fun yin, pe ìmọ́lẹ̀ ni Ọlọrun, òkùnkùn kò sì sí lọdọ rẹ̀ rárá. (1 Jhn 3:11.)

6. Bi awa bá wi pe awa ni ìdàpọ̀ pẹlu rẹ̀, ti awa sì nrìn ninu òkùnkùn, awa nṣèké, awa kò si ṣe otitọ́: (2 Kor 6:14; Jhn 8:55; 3:21.)

7. Ṣugbọn bi awa bá nrìn ninu ìmọ́lẹ̀, bi oun ti nbẹ ninu ìmọ́lẹ̀, awa ní idapọ pẹlu ara wa, ẹ̀jẹ̀ Jesu Kristi Ọmọ rẹ̀ nwẹ̀ wá nù kuro ninu ẹ̀ṣẹ̀ gbogbo. (Heb 9:14; 1 Pet 1:19; Ifh 1:5.)

8. Bi awa bá wí pe awa kò ni ẹ̀ṣẹ̀, awa tan ara wa jẹ, òtítọ́ kò sí ninu wa. (Job 15:14; Owe 20:9; Jms 3:2; 1 Jhn 2:4.)

9. Bi awa bá jẹwọ ẹ̀ṣẹ̀ wa, olootọ ati olododo ni oun lati dari ẹ̀ṣẹ̀ wa jì wá, ati lati wẹ̀ wá nù kuro ninu aiṣododo gbogbo. (Psm 51:2.)

10. Bi awa ba wi pe awa kòì tî dẹ́ṣẹ̀, awa mu un ni èké, ọ̀rọ̀ rẹ̀ ko sí ninu wa. (1 Jhn 5:10; 2:14.)

ORI 2.

EYIN ọmọ mi, iwe nkan wọnyìí ni mo kọ si yin, ki ẹ ma baa dẹ́ṣẹ̀. Bi ẹnikẹni bá sì dẹ́ṣẹ̀, awa ni alagbawi lọdọ Baba, Jesu Kristi olododo: (Rom 8:34; Heb 7:25.)